# AWỌN ILEPA ONIGBAGBỌ́

## Kolosse 2:20-23; 3:1-25

## ẸKỌ 411 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Njẹ bi a ba ti ji nyin dide pẹlu Kristi, ẹ mã ṣafẹri awọn nkan ti mbẹ loke" (Kolosse 3:1).**

### Ohun ti a N fẹ́

Ki ni ohun ti ọkàn n fẹ ju lọ lati ṣe ni ayé? Ki ni ilepa rẹ? Njẹ iwọ n fẹ́ lati jẹ́ alo-ohun-elo orin tabi akọrin ki o ba le maa lo ohun-elo orin tabi ki o le maa kọrin ni akoko isin ninu ile-isin? Iwọ ha n fẹ́ lati jẹ́ ajihinrere? Iwọ ha n fẹ́ lati maa waasu Ihinrere? Gbogbo ifẹ lati jẹ́ iranlọwọ fun awọn ẹlomiran ati lati ṣe rere ni ayé wọnyii n ti ọdọ Ọlọrun wá, bẹẹni eniyan a si maa fẹ́ lati ṣe nnkan wọnyii ki o ba lè wu Jesu.

Lonii, a o kà siwaju si i lati inu iwe ti Paulu Apọsteli kọ si awọn Onigbagbọ́ ti o wà ni ijọ Kolosse. Ọlorun ni o mí si Paulu lati kọ awọn ọ̀rọ wọnyii, a si pa ọ̀rọ rè mọ́ a si kọ ọ́ sinu Bibeli. Ọlọrun n fẹ́ ki gbogbo Onigbagbọ́ kà iwe yii. O ti jẹ́ iranlọwọ fun ọpọlọpọ eniyan lọjọ oni pẹlu gẹgẹ bi o ti ran awọn ara Kolosse lọwọ.

### Lati Inu Iku si Iyè

Awọn ti Paulu n kọwe si ti ni iyipada ọkàn nitootọ. Wọn ka ara wọn si okú si iwà ayé wọn atijọ. Wọn ti kọ ọ̀na ati ifẹ ti ara wọn silẹ wọn si n gbé igbesi-ayé wọn gẹgẹ bi apẹẹrẹ Kristi Ẹni ti o wá si ayé lati ṣe ifẹ Baba Rẹ̀ (Heberu 10:7). Awọn miiran ninu wọn jẹ́ Ju ti wọn ti n mú ẹbọ wọn wa si Tẹmpili ni Jerusalẹmu gẹgẹ bi àṣa, awọn miiran si jẹ́ Keferi ti wọn ti n gbiyanju lati tu ọlọrun wọn loju, awọn ọlọrun igi ati okuta. Ṣugbọn gbogbo wọn ni o ti ri i pe gbogbo aáyan wọn lati mu ki wọn di ẹni rere ti kuna. Ṣugbọn wọn mọ̀ ninu ọkan wọn pe ẹlẹbi ni wọn niwaju Ọlọrun.

Nigba ti wọn ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ wọn ti wọn si gba Jesu ni Olugbala wọn, a dari awọn ẹ̀ṣẹ wọn ji wọn a si sọ wọn di olododo nipasẹ ikú ati ajinde Kristi. Ni igbọran si aṣẹ ti Jesu ki O to pada lọ si Ọrun, a ti rì wọn bọmi gẹgẹ bi ẹri fun ayé pe awọn ti di okú si igbesi-ayé wọn atijọ ati pe a ti ji wọn dide pẹlu Kristi lati maa gbé igbesi-ayé ọtun ati eyi ti o yatọ.

### Wiwa Awọn Ohun ti O Wà Loke

Nisisiyii a gbé igbesi-ayé rere ti Onigbagbọ eyi ti wọn ti ṣe alabapin rẹ̀ ka iwaju wọn: "Njẹ bi a ba ti ji nyin dide pẹlu Kristi, ẹ mã ṣafẹri awọn nkan ti mbẹ loke." A paṣẹ fun wọn lati fi ọkan wọn tabi inu nwọn ṣafẹri awọn ohun ti Ọrun ki wọn si jẹki ṣiṣe ifẹ Rẹ̀ ki o leke ifẹ ohunkohun ti n bẹ ninu ayé. Ohun ti Ọlọrun ni wọn ni lati jẹ́ ki o gba ero wọn kan, ki i ṣe ohun ti ayé yii.

Lojoojumọ ki a to bẹrẹ si irò nipa ile-ẹkọ, nipa awọn ọ̀rẹ́, eré ṣiṣe, a gbọdọ kọkọ ri pe a ti bá Jesu sọrọ. Ẹsẹ ikẹẹdogun ati ikẹrindinlogun ninu ori-iwe ẹkọ wa fun wa ni amọran fun eto isin agboole ni owurọ tabi isin dida nikan gbadura. "Ẹ si ma dupẹ," eyi yii n damọran gbigba adura: Ninu ohun gbogbo, nipa adura ati ẹbẹ pẹlu idupẹ, ẹ mã fi ibere nyin hàn fun Ọlọrun" (Filippi 4:6). Jijẹ ki Ọrọ Kristi maa gbé inu wa ni ọ̀pọlọpọ ninu ọgbọ́n gbogbo ni lati maa kà ati lati maa ṣaṣaro lori apakan ninu Iwe Mimọ. "Ki ẹ mã kọ́, ki ẹ si mã gbà ara nyin niyanju ninu psalmu, ati ori iyìn, ati orin ẹmi," n dá lamọ̀ran lati kọ orin kan tabi meji.

Nigba naa, bi ọjọ ti n lọ bi idanwo ba dé, ronu nipa Jesu si ranti pe a ti fi iye rẹ pamọ pẹlu Kristi ninu Ọlọrun - a ti pa a mọ́ kuro ninu ayé. Wọn kò le ri idapọ didun ti o ni pẹlu Jesu ninu ọkàn rẹ, ṣugbọn wọn n ri ayọ̀ ti o hàn loju rẹ.

### Ti a Yà Sọtọ Kuro Ninu Ẹ̀ṣẹ

Ni kikú pẹlu Kristi, a ti yà wa sọtọ kuro ninu awọn ẹ̀ṣẹ wa nigba ti a gbà wá là. A ti "pa awọn ẹṣẹ wa run." Ki a ba le pa igbala wa mọ́, a nilati kọju ija si idanwo ki idanwo ti o n fẹ mu wa dẹ̀ṣẹ ti yoo sọ tẹmpili, ara wa eyi ti Ọlọrun dá lati jẹ́ ibugbe fun Ẹmi Mimọ́ Rẹ̀ di aimọ́.

Nigba ti a gba ọkan wa là a bọ́ ohun ti a le pe ni ẹ̀ṣẹ inu fùfù silẹ pẹlu. A tú wa silẹ kuro ninu ẹ̀ṣẹ iwa ibinu ti a kò lè ṣakoso rẹ̀, ẹmi igbẹsan, ọ̀rọ ti n panilara, ati irọ pipa.

### Gbigbe Awọn Oore-ọfẹ Ọlọrun Wọ̀

Nisisiyii ti a ti bọ́ awọn ẹ̀ṣẹ ti a n dá tẹlẹ silẹ, a ni awọn Oore-ọfẹ Kristi, eyi ti i ṣe iyọ́nú tabi aanu, iṣeun, ọkàn irẹlẹ, inu tutu, ipamọra. A nilati maa pọ̀ si i ninu awọn nnkan wọnyii ninu ayé wa siwaju ati siwaju.

A nilati le farada ki a si fi iṣeun hàn fun awọn arakunrin ati arabinrin wa ninu ile, awọn ọrẹ wa ni ile-ẹ̀kọ́, awọn ti o wà ni ile-isin ati awọn ti o wà lode bi o tilẹ jẹ pe wọn ki i ṣe ohun ti o tọ́ nigbagbogbo. A gbọdọ tẹle apẹẹrẹ Jesu. O dariji wá a si gbọdọ dariji awọn ẹlomiran. Bibeli wi pe, "Iwọ ki isi ṣãnu iranṣẹ ẹgbẹ rẹ, gẹgẹbi mo ti ṣãnu fun ọ?" (Matteu 18:33).

**Ifẹ Ọlọrun**

Leke gbogbo rẹ̀, tabi ni afikun si gbogbo ihuwa rere ti Onigbagbọ́ wọnyii, a nilati gbé ifẹ wọ̀ tabi ki a fi ifẹni kún un, eyi ti i ṣe ifẹ Ọlọrun. O lè wi pe, "Mo ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn mi nisisiyi." Eyi le jẹ bẹẹ, ṣugbọn a sọ fun awọn Onigbagbọ́ lati maa pọ̀ si i siwaju ati siwaju ninu ifẹ. Gbigbé ifẹ wọ̀ yii ni o n mú gbogbo iwa rere ti Onigbagbọ́ di pipé.

Ninu ohun gbogbo, i ba jẹ́ ti iṣẹ iṣoore tabi ọ̀rọ ti iranwọ ti a sọ tabi ti iwa rere ti a hù, a gbọdọ ṣe nnkan wọnyii nitori Jesu n fẹ ki a ṣe wọn, a si gbọdọ ṣe wọn gẹgẹ bi apẹẹrẹ ti O fi lelẹ̀.

**Awọn Ofin Akoso Iwa Hihù**

Iwe Paulu n sọ siwaju nipa awọn ofin akoso fun gbigbé igbesi-ayeé ti o dara, ti o si lérè laaarin ẹbi, ni ile-ẹ̀kọ́ ati ni ibi iṣẹ. Iya ati baba nilati jẹ́ oninuure ki wọn si jọ jumọ maa ṣiṣẹ pọ̀ ninu ile. Iya nilati bọwọ fun baba, baba si nilati kún fun ifẹ ki o si jẹ́ alagbara. Wọ́n nilati maa bá awọn ọmọ wi, ki wọn kọ́ wọn, ki wọn si tọ́ wọn, awọn ọmọ si nilati gbọran. Ki ni ṣe ti o ṣe pataki tobẹẹ lati gbọran? Nitori "eyi dara gidigidi ninu Oluwa."

A ri i ninu ẹ̀kọ́ wa oni pe, awọn ohun ti a n ṣe ati awọn ọ̀rọ ti a n sọ, igbesi-ayé ti a n gbé, gbọdọ jẹ́ eyi ti o wu Kristi. Nigba ti a ba lọ si ile-ẹ̀kọ́ ati nigba ti a ba lọ si ibi iṣẹ a gbọdọ gbọran si aṣẹ awọn ti o jẹ́ olori nibẹ, ki i ṣe nitori ki a le dé ipo giga, ki i ṣe kiki lati tẹ́ awọn oniṣẹ wa lọrun, bikoṣe nitori Ọlọrun n fẹ ki a gbọran, a si maa jẹ́ idunnu Rẹ̀ nigba ti a bá gbọran.

**Ere Ayeraye**

Ohunkohun ti ẹnikẹni bá ṣe ni aiye yii, i ba ṣe rere tabi buburu, Ọlọrun Ọrun on ayé n ri i. O ri ohun gbogbo; O mọ ohun gbogbo; olododo patapata ni Oun i ṣe, a o si gba ère bi a bá sin Kristi Oluwa. "Ṣugbọn ẹnikẹni ti o bá ṣe aiṣododo, yio gbà pada nitori aiṣododo na ti o ti ṣe: kò si si ojusaju enia."

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni itumọ pe ki a "kú pẹlu Kristi"?
2. Ilana wo ni a n pa mọ́ gẹgẹ bi ẹri fun ayé pe a n gbe igbesi-ayé titun pẹlu Kristi?
3. Ki ni itumọ pe ki a maa ronu awọn nnkan ti n bẹ loke?
4. Ki ni itumọ "nitorina ẹ mã pa ẹ̀ya-ara nyin ti mbẹ li aiye run"?
5. Darukọ awọn ẹ̀ṣẹ ti a le pe ni awọn ẹ̀ṣẹ ibinu.
6. Awọn oore-ọfẹ wo ni a nilati maa gbé wọ̀, tabi fikùn ayé wa, gẹgẹ bi Onigbagbọ́?
7. Ki ni ṣe ti a nilati dariji awọn ẹlomiran?
8. Ki ni "àmure iwa pipé"?
9. Awọn ẹsẹ meji wo ni o fi eto isin agboole lelẹ̀ ninu ori-iwe ẹ̀kọ́ wa?
10. Bawo ni ẹbi Onigbagbọ́ ṣe nilati maa gbé?